# PẸPẸ IDẸ: APẸẸRẸ IDALARE

## Ẹksodu 27:1-8; 38:1-7; 40:28-32;Lefitiku 6:1-7; 7:1-7

## ẸKỌ 72 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo" (1 Johannu 1:9).**

**I Pẹpẹ Idẹ ninu Agbala Agọ-Ajọ**

1 A fun Mose ni itọni kikún nipa gbigbe pẹpẹ idẹ naa ró, Ẹksodu 27:1-8; Heberu 8:5; 1 Kronika 28:11, 12, 19; Iṣe Awọn Apọsteli 7:44
2 A sẹ iṣẹ naa finni-finni gẹgẹ bi itọni Ọlọrun, Ẹksodu 38:1-7; Johannu 14:23; 1 Samuẹli 15:22; Jakọbu 1:25
3 A fi pẹpẹ naa si ibi ti ẹnikẹni ti o ba wọ inu Agọ ni lati gbà kọja, Ẹksodu 40:28, 29; Johannu 10:9; Iṣe Awọn Apọsteli 4:12
4 A gbe agbada omi saarin pẹpẹ ati Agọ́ gan an, Ẹksodu 40:30-32

**II Pẹpẹ Idẹ, Apẹẹrẹ Idalare**

1. Ẹṣẹ ẹni kan si ẹni keji jẹ́ ẹ̀ṣẹ si Ọlọrun pẹlu, Lefitiku 6:1, 2; 5:19
2. Ẹni ti o jẹbi naa ni lati mu ẹbọ irekọja wá fun Ọlọrun lati ri oju rere Rẹ̀, Lefitiku 6:2-6; 5:5, 6, 16; Ẹsra 10:19; Kolosse 1:14; Romu 5:6; 1 Peteru 3:18; Galatia 3:13; Heberu 2:9
3. Ẹni ti o ronupiwada naa ni lati ṣe atunṣe lọdọ ẹni ti o ti ṣẹ̀, Lefitiku 6:5; Esekiẹli 33:15
4. Ki ẹbọ to le jẹ itẹwọgba, o gbọdọ jẹ alailabùkù, Lefitiku 6:6; Isaiah 53:3-7; 2 Kọrinti 5:21; 1 Peteru 1:18, 19
5. A o wọ́n ẹjẹ rẹ̀ sara pẹpẹ idẹ a o si sun awọn apa kan lara ẹbọ naa lori rẹ̀, Lefitiku 7:1-5
6. Awọn alufaa yoo jẹ eyi ti o kù lara ẹbọ naa ni Ibi Mimọ́, Lefitiku 7:6
7. A o dárí ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ olurekọja naa ji i nipa ẹbọ ti o mu wa, pẹlu igbagbọ́ ati ironupiwada rẹ̀, nipa ṣiṣe atunṣe ọna rẹ̀, ati nipa ibuwọn ẹjẹ ti alufaa yoo ṣe, Lefitiku 6:7; Romu 5:9; 1 Johannu 3:5

## ALAYE

### Ibi ti Ọlọrun Bá Eniyan Pade

Ninu ẹkọ wa ti o kọja, a ri bi a ti ṣe èto kikọ́ Agọ naa lọna iyanu ati lẹsẹẹsẹ. A kiye si awọn otitọ kan ti a fi agọ naa ṣe apẹẹrẹ nibẹ; o duro fun awọn iriri nla mẹta ti Onigbagbọ: Idalare nipa Igbagbọ́, Isọdimimọ́, ati Ifiwọni Ẹmi Mimọ́. Nisisiyii a fẹ ṣe akiyesi awọn apẹẹrẹ nla wọnyii ni kikún.

Bi o ti jẹ pe Agọ naa duro fun sisun mọ Ọlọrun ti eniyan, ati ifarahan Ọlọrun tikara Rẹ̀ fun eniyan, a ri i pe agbala jẹ apẹẹrẹ idalẹbi fun ẹ̀ṣẹ. Ko si ẹni ti o le wọ Agọ naa a fi bi o ba kọkọ tọrọ idariji lọdọ Ọlọrun. Ifarahan Ọlọrun wà nibi mimọ́ wọnni, ko si si ẹni ti o gbọdọ wọ ibẹ bi ko ṣe awọn ti Ọlọrun ti yàn si iṣẹ-isin Agọ. Awọn Ọmọ Israẹli pagọ si àye ti a fi olukuluku si, Agọ Ajọ si wà ni aarin. Eyi mu ki o rọrun fun gbogbo wọn lati le wá sibẹ, ṣugbọn nitori ifarahan Ọlọrun, ibẹ jẹ ibi ọ̀wọ̀ gidigidi. Kiki awọn olufọkansin ati onirobinujẹ ẹlẹṣẹ nikan ni o le sun mọ ibẹ, nitori ibẹru idajọ ojiji ti o daju lori awọn miiran ti wọn ba ṣe lodi lati wá sibẹ.

Awọn Heberu ti igba aye Mose ko i ti dagba tó fun alaye ti Jesu ṣe fun obinrin ni lẹba kanga Sikari nipa iwa Ọlọrun ati isin Rẹ̀ (Johannu 4:21-24). O gbà pe ki Ọlọrun tọ́ araye ni ṣiṣẹ̀ n tẹle ki ilana Rẹ̀ ba le ye ni. Ofin ti a fi fun ni ati idasilẹ isin Agọ jẹ iṣisẹ kan lati mu eniyan sun mọ Ọlọrun; Israẹli sì ni ohun elo Ọlọrun nipa eyi ti o fẹ lati sọ ifẹ Rẹ̀ di mimọ̀ fun gbogbo aye.

### Imuṣẹ Awọn Apẹẹrẹ Naa

A le ri i nigba naa pe a kọ́ Agọ naa lati ṣe apẹẹrẹ pupọ ninu awọn otitọ Ihinrere ti wọn ṣe iyebiye, diẹ ninu eyi ti o le ye awọn Ọmọ Israẹli ti igba naa, ṣugbọn awọn miiran ni a pamọ́ titi di ọjọ iwaju. Bawo ni o ṣe yẹ fun wa lati maa dupẹ tó pe a ni anfaani lati wà laaye ni akoko ti Ọlọrun tú ibukun Rẹ̀ jade fun eniyan ni odiwọn ti o gadabú to bayii! A kò tun duro mọ lẹyin agbala nigba ti ẹlomiran ba lọ si Ibi Mimọ́ Julọ lati bẹbẹ fun wa! A le wọle fun ra wa ki a si gbadun anfaani biba Ọlọrun sọrọ taara fun ra wa. Ẹmi Mimọ́ le fi ọkàn wa ṣe tẹmpili Rẹ̀ nisisiyii ki o si maa gbé inu wa, dipo ki o kàn wà pẹlu wa (Johannu 14:16-18).

Ẹlẹṣẹ ti o mọ ẹbi ẹ̀ṣẹ rẹ a tọ Ọlọrun wá nipa wiwa si ẹnu-ọna agbala Agọ. Oun a mu ẹbọ wa fun irekọja rẹ̀, nitori bi o ti wù ki aniyan rẹ̀ ti pọ to lati ri gbogbo ibukun ti Ọlọrun ni fun un, oun ko le ri awọn ibukun ti a ṣeto rẹ fun Ibi Mimọ́, tabi Ibi Mimọ́ Julọ gbà, ayafi lẹyin ti o ba kọ́kọ́ wá sinu agbala ti o wà lode ati sibi pẹpẹ ẹbọ sisun. Aye pẹpẹ yii ninu agbala fi hàn pe a kò le de ọdọ Ọlọrun a fi gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ ti a ti dalare nipa Ẹjẹ Kristi.

Ọlọrun fi aṣẹ lelẹ nipa oriṣiriṣi ẹbọ pupọ, ọkọọkan fun iṣẹ kan pataki ati lati dí àyè kan; ṣugbọn Jesu gẹgẹ bi Ẹbọ Pipe mu gbogbo rẹ ṣẹ. Isin igba naa jẹ iṣisẹ kan ṣaaju ki Ẹbọ arukun ati aruda yii to de, olusin a si fi igbagbọ wo ọjọ iwaju nigba ti a o ṣe irubọ naa, ṣugbọn awa n fi igbagbọ wo ẹyin nitori a ti ṣe irubọ naa kọja.

**Bi a Ṣe Kọ Pẹpẹ Naa**

Pẹpẹ naa ni ihò ninu nitori patako ni a fi ṣe e a si fi idẹ bo o. Gigun rẹ ati ibú rẹ jẹ ẹsẹ meje ati àbọ dọgbadọgba, o si ga ni ẹsẹ mẹrin ati aabọ. Ọna iyanu ni a gbà tan ina sori rẹ, bẹẹ ni ina naa ki i kú, nitori awọn alufaa maa n fi igi si i lati igba de igba bi o ti tọ́ (Lefitiku 6:9; 9:24). Ni ọkọọkan igun rẹ mẹrẹẹrin ni iwo kan wà nipa eyi ti awọn kan ti sọ oriṣiriṣi ọrọ. Onipsalmu mẹnu ba iwo bi ohun ti a fi n so ẹbọ mọ pẹpẹ (Orin Dafidi 118:27). Boya wọn bùkún ẹwà pẹpẹ pẹlu. Ninu Iwe Mimọ́ a kà nipa awọn ti wọn di iwo wọnyii mu bi wọn ti n fi ọkàn ibanujẹ gidigidi gbadura si Ọlọrun. Nipa ilo, pẹpẹ naa jẹ ibi aabo nigba ti wọn ba fẹ gbẹsan lara ẹni kan ti o ṣeeṣi pa ẹlomiran lara. Ṣugbọn lasan ni ẹni ti o mọ̀ọ́mọ̀ paniyan wá sibẹ fun aabo, nitori nipa aṣẹ Ọlọrun a le wọ́ ọ jade fun idajọ.

**Ohun ti Ẹbọ Irekọja Wà Fún**

Lati atetekọṣe ni wọn ti n rubọ. Inu Ọlọrun dùn si ẹbọ Abẹli; nitori naa a le kà a si pe a ti sọ fun un iru ẹbọ ti o tọna. A ko yi ilana yii pada ri, àyàfi nigba ti a dá isin Agọ silẹ. Noa, Abrahamu, ati Jobu rubọ si Ọlọrun. Nipa igbagbọ wọn ninu Ọlọrun, wọn ri idahun gbà, igbesi aye wọn si jẹri si i pe wọn wu Ọlọrun.

Ẹbọ irekọja fi pipe iwa mimọ́ Ọlọrun hàn, otitọ nla ti o si ni ironu, o si jẹ ẹ̀ri pe eniyan ṣe alaini iwà mimọ yii rara. O fi hàn pe iyà iku ni o tọ́ si ẹni ti o mu ẹbọ naa wa ati pe ẹni kan ni lati kú dipo rẹ lati mu idajọ ṣẹ, bi ko ṣe bẹẹ oun yoo ṣegbe. Bi a ṣe fi pẹlẹpẹlẹ yan ẹbọ naa fi hàn pe eto kan wà ti a gbọdọ tẹle finnifinni, ati pe ẹbọ naa gbọdọ jẹ eyi ti o wu Ọlọrun gẹgẹ bi O ti beere rẹ. Bi a si ti n fara balẹ yẹ Ọrọ Ọlọrun wò ti a si n ri ifẹ Rẹ fun wa, a ṣe akiyesi pe awa naa kò le ṣe ohun ti o dinkù si eyi – bi o tilẹ jẹ pe a kò tun beere iru ẹbọ ti Majẹmu Laelae mọ́ lọwọ wa, niwọn bi Ọdọ Agutan Ọlọrun ti tú Ẹjẹ ti Rẹ jade fun idariji ati irapada wa.

**Atunṣe -- Nigba Nì ati Nisisiyii**

O tun ku ohun kan ti ẹni ti o dẹṣẹ ni lati ṣe. O gbọdọ ṣe atunṣe fun ẹ̀ṣẹ irekọja ti o ti ṣẹ̀ si Ọlọrun tabi eniyan. O tun ni lati fi ele sori iye ohun ti o fi du olohun lati fi dí adanu ti olohun pa laaarin igba ti o dá ẹ̀ṣẹ naa ati igba ti o ṣe atunṣe. Atunṣe jẹ́ ọ̀kan ninu awọn otitọ inu Bibeli ti awọn eniyan n gbiyanju lati yẹra fun lode oni.

**Ni Ipo Wa**

Ẹbọ irekọja yii jẹ ikede gbọnmọ gbọnmọ si Ju ati Keferi pe gbogbo eniyan ni o ti jẹbi gidigidi niwaju Ọlọrun, wọn ko si le wá sọdọ Rẹ tabi ki wọn ri oju rere Rẹ afi nipa Ẹjẹ nì. "Ẹjẹ!" ni igbe atayebaye ti kò si dẹ́kun, ti Ofin n ké rara si olukuluku ẹni ti o rú aṣẹ rẹ, o si di igba ti igbe yii ba rọlẹ ti a si ṣe ohun ti o n beere ki ẹnikẹni to le ri oju Ọlọrun ki o si yè.

Ẹni ti o mu ẹbọ naa wa gbọdọ gbà pe ti oun ni; pe oun mu un wa fun irekọja oun; pe oun yẹ si iku; ati pe oun n bẹ Ọlọrun ki O tẹwọ gba ẹmi ẹranko alaiṣẹ yii dipo ẹmi ti oun. Lẹẹkan si i, a tun n sọ pe gbogbo eyi n tọka lọna kan tabi omiran (nipa igbagbọ́) si Ẹni ti a n bọ̀ wa fi ẹmi Rẹ ṣe ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ.

A ṣe etutu nipa fifi ẹjẹ wọ́n pẹpẹ. Ofin beere pe ki a fi ẹmi kan ṣe irapada ẹmi miiran; nitori naa o ṣe danindanin pe ki a ri ẹni ti yoo kú fun eniyan. Ẹlẹṣẹ kan kò le kú fun ẹlẹṣẹ miiran, nitori oun naa ti wà labẹ idajọ ikú fun ẹ̀ṣẹ ara rẹ. Nitori eyi Ẹni kan ṣoṣo ni o le de oju ami gbogbo ohun ti Ọlọrun n beere. Ẹni naa ni Jesu, nitori Oun nikan ni kò dẹ̀ṣẹ. Ẹbọ ti a fi ẹranko ti kò le fọhun ṣe ki ba ti le wulo rara bi ko ṣe nitori o jẹ apẹẹrẹ pe Ọdọ-Agutan Ọlọrun n bọ̀ wa lati wa fi ẹmi Rẹ lelẹ fun irapada ọpọ eniyan.

Eyi ni a n pè ni ẹ̀kọ́ ṣiṣe aropo, ti ọpọ eniyan lodi si. Awọn kan n jiyàn pe ko le ṣe e ṣe; awọn miiran si n sọ pe o jẹ iwa aidọgba bi o ba ri bẹẹ. Ṣugbọn ero ti Ọlọrun ki i ṣe ero ti wa. Ọpọ ohun ijinlẹ ni eniyan kò i ti ronu kàn, bẹẹ ni ilana idajọ pupọ ni ko i ti wọ inu ọmọ eniyan lọ; ki ni ṣe ti a o si fi arosọ ọgbọ́n ti wa ti o kuru tako ifihan eto ti o jinlẹ ti o si gbooro ti i ṣe ilana Ọlọrun.

**"Ẹnikẹni ti o ba Fẹ"**

Otitọ miiran wà ti o yẹ ki a kiye si nipa irubọ yii, eyi si ni ominira pipe fun "ẹnikẹni ti o ba fẹ" lati ṣe irubọ naa ki o si di alabapin awọn ibukun rẹ. A ko diwọn akoko kan fun un: "Lonii ni ọjọ igbala." Anfaani naa si ṣi silẹ ni akoko kan gẹgẹ bi ni akoko miiran, a si le mu un lò nigbakigba ti ẹnikẹni ba ni ilo rẹ.

Bi ẹni ti o ronupiwada naa kò ba le ri ọdọ-agutan mu wa, a le tẹwọ gba adaba tabi ẹyẹle bakan naa. Niwọn bi wọn ti jẹ ẹyẹ ti a le ri mú ninu igbẹ, aini owo lọwọ kò di ẹnikẹni lọwọ lati ri mu wa. Gbogbo ohun ti eniyan ni i ṣe ni pe ki o wá pẹlu iyọọda ati ipinnu ọkàn rẹ. Eyi ko ṣeeṣi ri bẹẹ lasan. A gbe e kalẹ bẹẹ lati fi otitọ Ihinrere hàn, ipe si gbogbo agbaye lati ronupiwada.

**Bi Ẹni ti a ti Dalare rí ba ṣe Aigbọran si Ọlọrun**

Bi ẹni kan ba ṣẹ̀ si ofin Ọlọrun lẹyin ti o ti n pa ofin wọnni mọ́, ẹtọ ni fun un lati mu ẹbọ irekọja miiran wá, ki o si tọrọ idariji fun irekọja naa. Eyi jẹ atako miiran lati inu Iwe Mimọ́ lodi si ẹkọ kan ti o gbode kan lonii pe "ẹnikẹni ti o ba ti ni igbala lẹẹkan ti di ọmọ igbala titi ayé" bi o ba tilẹ ṣe pe iru ẹni bẹẹ tun pada sinu ẹ̀ṣẹ. Bi ẹni kan ba ṣẹ̀

si Ọlọrun tabi si eniyan o gbọdọ mu ẹbọ miiran wá ki o si tun tọrọ idariji ki a to gba fun un lati ni ipin kankan pẹlu awọn eniyan Ọlọrun tabi lati sin Ọlọrun ninu Agọ Rẹ̀.

**Ẹbọ Owurọ ati Aṣaalẹ**

Fun anfaani awọn Ọmọ Israẹli Ọlọrun tun ṣe ilana ẹbọ sisun. Ninu ilana yii a ni lati maa rú ẹbọ sisun lẹẹmeji lojumọ, lowurọ ati ni aṣaalẹ, bẹẹ si ni ẹbọ miiran wà fun ọjọ Isinmi ati awọn ọjọ miiran ti a yà sọtọ, bi Ọjọ Etutu. Wọn si tun ni àye ti wọn ni akoko wahala, nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ba ri i pe o yẹ ki wọn sun mọ Ọlọrun si i gẹgẹ bi orilẹ-ede tabi gẹgẹ bi ẹni kọọkan.

Nigba pupọ ni Israẹli fi isin tootọ naa silẹ, wọn si yi pada ni akoko kan kuro ninu ẹmi ijọsin ti igbagbọ ati ironupiwada to bẹẹ ti Ọlọrun ka ẹbọ wọn si irira. Ṣugbọn niwọn igba ti wọn ba wà ninu ẹmi ijọsin tootọ wọn ni lati maa rú ẹbọ sisun fun iranti ni igba gbogbo pe Iru Ọmọ ti satani yoo pa ni gigisẹ n bọ̀ wá (Gẹnẹsisi 3:15), Ọlọrun a si tẹwọ gba ẹbọ naa.

Awọn ẹbọ wọnyii kò mú irekọja ẹni kọọkan kuro, ṣugbọn wọn jẹ apẹẹrẹ awọn ibukun ti a o gbà ninu etutu gbogbo-nṣe kan: wiwẹ ọkàn wa lojoojumọ ninu Ẹjẹ nì, iwosan ara wa, iwẹnumọ igba gbogbo, ati iranwọ lẹsẹkẹsẹ ni akoko idaamu tabi ewu. Ṣugbọn ẹlẹṣẹ tabi afasẹyin gbọdọ mu ẹbọ irekọja ti rẹ̀ wá fun idariji irekọja rẹ̀.

Iyanu ni o jẹ pe gbogbo ilana irubọ ninu ofin ni a mu ṣẹ patapata ninu Kristi. O kú ni Kalfari lati mu gbogbo irubọ wọnyii ṣẹ, nitori a kàn An mọ́ agbelebu ni akoko ẹbọ owurọ, O si jọwọ ẹmi Rẹ̀ lọwọ ni akoko ti wọn maa n pa ẹbọ aṣaalẹ. Awọn Ọmọ Israẹli maa n pejọ niwaju agbala lati jọsin nigba ti a ba n pa ọkọọkan ninu awọn ẹbọ sisun wọnyii; ati ni mimu eyi ṣẹ, awa maa n pejọ ni Ile Ọlọrun Ọrun ti o rán Ọdọ-Agutan pipe naa wá lati kú fun wa.

Nipa gbogbo nnkan wọnyii a le ri diẹ kinun ninu ifẹ ati aniyan Ọlọrun fun iran ti o ti ṣubu. Ọna Rẹ̀ ti jẹ iyanu to! Eto Rẹ̀ si ti jẹ ẹ̀kún rẹrẹ to, paapaa bi o ti jẹ pe a ṣe wọn lati tán aini ti ẹmi eniyan ti ki i kú! "Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkàn: irobinujẹ ati irora aiya, Ọlọrun, on ni iwọ kì yio gàn" (Orin Dafidi 51:17).

## AWỌN IBEERE

1. Nibo ni pẹpẹ idẹ wà si Agọ naa?
2. Ki ni titobi rẹ̀, bawo ni a si ti kọ́ ọ?
3. Ki ni ohun miiran ti o sun mọ ọn?
4. Ki ni ṣe ti ẹbọ ẹ̀ṣẹ fi ṣe pataki bẹẹ?
5. Ki ni gbogbo ẹbọ wọnyii n tọka si?
6. Ki ni àgbalá duro fun?
7. Iriri Onigbagbọ́ wo ni ẹni ti n ronupiwada maa n ri gbà nigba ti o ba wá si ibi pẹpẹ idẹ pẹlu ẹbọ rẹ̀?
8. Ki ni gbọdọ wà ninu ọkàn ẹni ti o ronupiwada naa nigba ti o bá wá?
9. Bawo ni a ti n ṣe etutu fun irekọja?
10. Ka Isaiah 1:2-20 ki o si sọ idi rẹ̀ ti ẹbọ wọnni ti a darukọ kò fi jẹ́ itẹwọgba.